# ELETI-ỌFẸ

A-NJU-WON KO ṢE WI LẸJỌ

VOL. XIV NO 820 LAGOS SATURDAY MAY 19. — MAY 25. 1962. KỌBỌ MEJI (2D)


# Enia Pupo Lo Ku Si Meka L'odun Yi

## Medogun Ni Ti Nigeria

Mẹka—Ni oru ọjọ Alamisi ijẹta mọjumọ ọjọ Jimọ ana, ni a ri wosika kan gba lati ọwọ onirohin wa kan ninu awọn ti nwọn lọ si Mẹka lọ ṣe'Hadji lọdun ni; ninu iwe rẹ na, o ni awọn ti o ku si Mẹka (ninu ogunlọgọ enia ti o wa lati gbogbo agbaiye) ju igba enia lọ. O ni awọn ara ilu Nigeria ti o ku, ti nwọn sọ fun awọn nibiti awọn gbe wọsi to enia bi mẹdogun.

Diẹ ninu iwe rẹ ti o kọ si wa na niyi: "Ẹ jọwọ, ẹ maṣe binu wipe ẹ ko tete ri iwe mi lati igba ti mo ti de ilu Mẹka, wahala a mbọ sihin, a mbọ sọhun ni kojẹ, ṣugbọn mo kọ iwe kan si nyin lọjọ ti mo gunlẹ si ebute Jẹdda nigbati a nlọ.

"A ti gun oke Arafa, nisisiyi olukuluku nmura lati pada si ile rẹ. Wahala ti a kọkọ ri nibi, ni ti oru-mimu, gbogbo rẹ ngbona foo. Eyiti o wa pa-bambari nibẹ ni t'ọjọ ti a nyi okuta Kaba ka, ogunlọgọ enia ni nwọn tẹ pa nibẹ. A gbọ wipe o to enia mẹdogun tabi jubẹlọ to ku ninu awọn ara (Nigeria) wa. Nwọn ni awọn kan Hausa ninu awọn ti o ku na, pẹlu ara Ilọrin kan, ati ẹnikan ni Ijẹbu, ṣugbọn a koiti mọ orukọ gbogbo wọn. Ẹ ba wa ṣe adura ki Ọlọrun ṣọ awa yoku de ile pẹlu alafia."


Advertisement No. 76.

## KERE O

OFIN TI A NFI NA OWO

ATIJỌ (WEST AFRICAN CURRENCY BOARD NOTES & COINS)

DI PI PARẸ

A fẹ la ti ran gbogbo ẹnyin enia leti wipe lati ọjọ Kini oṣu July, 1962 (Oṣu keje ọdun yi) gbogbo Owo atijọ patapata eyi ni owo Pepa ati owo Ṣile titi de ori Epini yio kunọ. Ako ni le lo wọn gẹgẹ bi ofin ni ilẹ Nigeria.

Eyi ni wipe lati ọjọ Kini oṣu keje (July) ọdun yi, Owo atijọ wọnyi koni wulo fun sisan owo fun iṣẹ aje ni jake-jado ilẹ Nigeria - fun apejuwe, akoni gba fun ọja rira tabi fun ọja tita ninu ọja ati ṣọpu.

Gbogbo eni ti o ba ni owo atijọ wọnyi lọwọ tabi ni ipamọ yala ni Pepa tabi ni Ṣile ni lati tara lọ ṣe paṣi parọ owo wọnyi ni Bank ki Bank fun owo titun eyiti Central Bank ti Nigeria fi sita ni nkan bi ọdun kẹta sẹhin, ti asi nna lọwọlọyi, ki ọjọ Kini oṣu keje ọdun yi (July) to to - Ọfẹ ni gbogbo Bank yio parọ Owo wọnyi fun yin.

JOHN BEACH
Deputy General Manager.

Central Bank of Nigeria,
Lagos.


## Akara Tu S'epo! Edeaiyede Nla Besile Ninu Egbe Afenifere

EKO—Edeaiyede irufẹ eyiti a ko gbọri, ti a ko ri ri, eyiti ko ṣe gbọ tabi ti ko ṣe ro ni o bẹsilẹ larin awọn Ọgagun ọkọ ẹgbẹ Afẹnifẹre. Edeaiyede na bẹ silẹ bi igbati apara san ti ọmọ inu rẹ tuka larin Oloye Ọlọla Obafẹmi Awolọwọ ati Igbakeji rẹ Oloye Akintọla ti o nṣe Olotu Ijọba Iwọ-Orun, Nigeria.



OLOYE S. L. AKINTỌLA, OLOTU IJỌBA IWỌ-ORUN

### PANTIWA?

Ohun ti o fa sababi ija na nipe ẹnikini nsọ wipe "afi on, afi on" ẹnikeji nsọ wipe "afi on, afi enia". Ki eleyi jẹ ẹda ọrọ, ki o si ma a ro kii ninu awọn apa kinni ati keji ọrọ yi. Ẹniti o wipe "afi on, afi on" mọ ara rẹ, ni idakeji ẹwẹ, ẹniti o wipe "afi on afi enia" mọ ara rẹ.

Orişirişi tẹmbẹlẹkun ni ọrọ yi ti fa silẹ larin awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre jake-jado igun mẹrẹrin ilẹ Nigeria titi lọ de ilẹ Ghana ati ilu Oyinbo. Awọn apakan fi ara mọ ẹsun ti Oloye Awolọwọ fi sun Igbakeji rẹ, bẹni ogunlọgọ


(Wo yoku loju ewẹ kẹjọ)

## AWO IRAWO

Ey. ni awọn nkan ti yio ṣẹlẹ si ọ ni ọsẹ ti o mbọ.

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Awọn enia ti irawọ re ba bamu ni wa ba rie pọ nnu ọsẹ yi.

PISCES (Feb 21-Mar 20) Ti o k ba fẹ ba s kan ẹ fun a/a rẹ awọn ọrẹ ti o ṣe f'ehinti ni ki o sọrọ aṣiri fun.

ARIES (Mar 21-April 20) Ọrẹ tuntun ti o ba pade ninu ọsẹ yi le mu nkan le die fun ọ.

TAURUS (April 21-May 20) Bi nkan ko ba ri bi o ti ro si, maṣe binu rara, gbogbo nkan yio dara.

GEMINI (May 21-June 21) Boya nwọn le fi ọrẹ iṣn ajo lọ ẹ, ki o lọ, alọ ati abọ a dara.

CANCER (June 22-July 23) Awọn gbese kan wa ti o ni lati tete yanju lọse yi.

LEO June 22-(July 23 Ki o fi irẹlẹ ati ọgbọn ba awọn enia lo larin ọsẹ yi.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Ṣọ ara re pupọ pelu alejo tuntun. Wa ri obinrin tabi ọkunrin ti yio fo ife si ọ.

LIBRA (Sep 24-Oct 23) Awọn ọrẹ kan a fun ọ ni imọran ti o dara.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Maṣe ba awọn ọrẹ rẹ ṣe gbolohun-asọ rara.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Iwe ṣoki ni ki o kọ ti o ba nkọwe si enia.

CAPRICORN (Dec 34-Jan 21 Ti o ba bọ si'ta wa ri enia-rere ba ṣ'ire; maṣe fo'ya rara.

# Baba Kan Ku Nibiti O Gbe Npa Eran Ileya

Ibadan—Gbogbo awọn iyawo ati ibatan Alufa kan ti orukọ rẹ njẹ Aruna Atanda, ni idamu ba nigbati Alufa na ṣubu lulẹ ti o si ku patapata nibiti o gbe ti ndubu ẹran Ileya ti o pa fun ọdun lọwọ.

Akọwe onirohin wa ni, ti Ọgbẹni na ti pada de si ile rẹ ni opopo Amunigun lati Mọsalasi Ọdun ti o ti lọ kirun idupẹ, wipe Ọlọrun da on si, on ti ri ọdun miran, ni o ba ni ki awọn ọmọ on mu agbo-ola ti on ti ra fun idupẹ ọdun na jade ki on paa.

Bi o ti pa agbo na tan, ti o ni ki nwọn gbe omi fun on ki on fi ṣan'wọ ati ọbẹ ni o ba ṣubu lulẹ ti o si ku patapata.

BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

Fun ina dídá ati fun imọlẹ

BP SUPERLITE KEROSINE

L'ayo!




Ti o ba ṣepe Kerosine lo fẹ BP Superlite l'ayo o le ri rà nibikibi, ko si wọn, o mọ daradara, owun lo si dara ju fun onje-sise, iná-titàn ati lati mã fi yinà Kerosine ti oti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!

## OLOPA OBINRIN LORIESIN



M. D. N. Catherine Evana ti a nwo aworan rẹ lori ẹṣin yi jẹ ọlọpa obinrin ti o kọkọ gun ẹṣin ṣiṣẹ ni Manchester nilu Oyinbo.

Catherine ti bẹrẹ si gun ẹṣin nigbati o wa ni ọmọ ọdun meje ki o to wọ iṣẹ Ọlọpa ni oṣu March ọdun tokọja, iṣẹ olotọju ẹṣin l'o ti nṣe tẹlẹ ri.

# Eko - Akete Ile Ogbon

## Lati Owo Olalekan Onatade

Ni aipẹ yi ni emi pẹlu agbalagba kan ti o jẹ ọkan ninu awọn ti a tijọ s'ere pọ nsọrọ ni ibi aṣeyẹ kan ni Eko. A sọ ọrọ wa na titi, a wa mu ẹnu kan igba ti a maa nja gidigbo larin Eko ati bi a ti maa nṣ'ere ninu ebutu ti o pọ nigbana l'Eko, ati bi kokoro kekere kan ti nwọn npe ni jiga ti nma nṣe wa l'ọṣẹ.

Ọrọ na wa jẹ ki nrẹrin titi, o tun mu mi niran ọkan ninu awọn orin atijọ na ti a nkọ lọmọde l'agba: "Eko Akete Ile Ọgbọn".

Ninu ọrọ mi l'ọsẹ yi, diẹ ni mo fẹ mu ẹnu kan nipa bi Eko tiri nigbati emi mba wọn ṣe ọmọde ni ilu yi, ati iru ọkọ wo ni awọn enia wa lati ilu-oke nwọ wa si Eko.

Nigbati awọn Oyinbo ọlọkọ'lẹ ti ẹ npe ni reluwe kọ bẹrẹ, ilu Abẹokuta ni nwọn duro si, orukọ ti nwọn si njẹ ni Lagos Railway. Awọn Ẹgba (ara Abẹokuta) kotilẹ fẹ ki nwọn gba ọdọ awọn rara. Nwọn fi logun l'ọgbọn, asẹhinwa, asẹhinbọ, awọn agbalagba ọmọ'we ilu na dide si ọrọ na, eleyi wa jẹ ki awọn Ijọba Oyinbo aiyegbani ba awọn Ẹgba ṣe adehun.

Tẹlẹtẹlẹ gbogbo awọn ara Abẹokuta ti o ba fẹ mu ekurọ ati epo wa si Eko, ọkọ oju omi ni nwọn nlo lori odo Ogun; irin ajo yi si ngba wọn ni ọsẹ kan tabi ọjọ marun.

Loni, iru irin ajo bayi ni o mu ọpọlọpọ ọmọ Ẹgba di ara Ikorodu, nitoripe ọpọlọpọ nwọn nigbati nwọn nwa ọkọ oju-omi wọn bọ wa si. Eko ni nwọn fi ebute (Ikorodu) yi ṣe ibudo si. Lojọ oni ni, igboro ilu Abẹokura wa ma gbọ ti nwọn ba nki awọn elomiran "Ara Ojowo".

Ibiti awọn ọlọkọ Ẹgba ni aiye igbana ma nduro si ni nwọn npe ni Ebute-Ero titi di ọjọ oni, ṣugbọn aye ti awọn onisowo Ẹgba yi ma nduro si gaan ni Itọlọ (Ebute Olowogbowo) leti ọdọ awọn Oyinbo onisowo.

Nigbana ni awọn ọmọ iya wa lati ilu Saro ati Libiria (Liberia) ti nwọn npe nwọn ni Kurumọ ni nwọn nkun adugbo Olowogbowo na ati awọn ọpọlọpọ awọn onisowo Ẹgba ti nwọn si nlọ si ile-iwe ati awọn ti nwọn ti pari ẹkọ wọn ti nwọn nmura lati lọ si ilu Ọba (bi nwọn ti npe ilu Oyinbo niyẹn ni igbana) fun isẹ lọya ati dokita

Idi ọrọ niyi, ti emi na ma nfi ọwọ sọ aya mi wipe ọmọ Olowogbowo ni mi, nitoripe ni Olowogbowo, l'Eko ni mo ṣe ere ọmọde pẹlu awọn Kurumọ.

Idi rẹ ti nwọn ṣe npe awọn ọmọ iya wa ti o wa ṣe iṣẹ nilu yi ni Kurumọ maa mọ sọ itan na fun nyin ninu iwe yi nigbamiran.

OLOWOGBOWO L'ONI GIDIGBO

Lori tani o l'agbara ju enia kan lọ ni a fi bẹrẹ ija gidigbo l'Eko pẹlu awọn enia wa ti nwọn npe ni "Kurumọ" di ọjọ oni. Ti awọn Kurumọ na ba ti ṣe tan nibi ijẹ wọn, nwọn a wipe o ya o, aburo, ki a lọ da'raya.

Awọn ara wa yi (Kurumọ) ni o jẹ ki ọpọlọpọ wa mọ lati wẹ ninu odo; nitoripe nigbana kosi "f'ayawọ", ko si "ọmọmeji dawolẹ". Olukuluku mọ agbalagba ni agbalagba. Awọn ọmọ Musulimi mọ ara wọn ni Musulumi, ofin si ni, ni agbo-ile wọn wipe, nwọn ko gbọdọ ba awọn ọmọ Onigbagbo ("Kiriyo") ṣe nkankan pọ.

Ni aiye igba na, ibẹru wa ni ara awọn agbalagba; kọ ba jẹ Kiriyo tabi Imale. Ni Olowogbowo, gbogbo nkan wa ndun yungba bi agbayun. Awọn alaredẹ ngbọ to'kọ, awọn ọkọ wọn paapa ngbọ ti alarede.

ONJẸ PỌ, AIYE DARA

Nkan opẹ, bi irẹsi, boia buredi, ẹja inu agolo, ti ẹ npe ni Sandini wa pọ ni ilu. Aṣọ paapa (ko nṣe aṣọ ti nwọn fi eepo ireke ṣe) wa pọ ni pupoju nilu.

ṢỌBU ONI PETẸSI

Awọn Oyinbo ajoji (French Coy) ni o kọ lo il -ṣaja oni petẹsi l'Eko, nibikanna ni nwọn si wa ni Ẹnin-Igbẹti di ọjọ oni.

Nwọn kii ṣe Oyinbo kan ti o n suru. Bi o ba jẹ akọwe-ijọba l'ọdọ wọn, o ni lati mọ iwe kọ pelu iyara. Ewe-taba ni o fẹ ra ni, tabi aṣọ.

(Koti pari)

# ERE IDARAYA BOLU AFESE GBA



Aworan ti a nwo yi niti awon egbe agba bolu meji

**Wolverhampton Wanderers ati West Bromswich Albion ti fi bolu afese gba sere ije lori Ife kan ni Wolverhamption, England.**

**Awon egbe ti West Bromswich ni o bori ninu ere ije na pelu agba wole meji si okan ti Wolverhampton Wanderers.**

# ELETI--OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS

28, Kosọkọ Street, Lagos. "ELETI OFẸ," LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370.

VOL XIV. No. 810. SATVRDAY MAY 19- MAY 25, 1962


# Yoruba Meta, Egbeta Enmo !

OWE nla oke yi ni a fiṣe eṣin wosika wa ọsẹ yi fun ẹnyin ọkawe wa. Ohun ti o fa sababi ọrọ owe wa na ni wipe ninu iran ti Oluwa Ọlọrun da, iran Yoruba ni o buru julọ.

Bi a ba nwa ibiti ọtẹ gbe gbilẹ si, arın Yoruba ni, bi a ba nwa tẹmbẹlẹkun, arin Yoruba ni, bi a ba nwa iṣubu ọmọ ẹnikeji ẹni, arin Yoruba ni ao ti ri. Bi a ba nba lọ bayi, ao ri to ẹgbata oniruru iwa buburu ti o wa l'arin awọn Yoruba.

KI DEDE BINU

Aṣiwere lo nfa, ohun ti o mu wa sọ gbolohun ọrọ yi ni pe awa Eleti—Ọfẹ ti Lanujẹ pupọ nitori ọrọ ti o bẹ silẹ larin awọn Olotu ẹgbẹ Afẹnifẹre mejeji, ko si nṣe ifẹ inu wa rara lati da si ọrọ na tabi lati da, ẹnikan l'ẹjọ, ṣugbọn ari wipe bi awọn agba-agba ati awọn ẹniti o ri rẹ pe bi Oloye Rotimi Williams ti nṣe eto ti nwọn si nsa agbara pe ki ọrọ yi mupo, bẹni awọn majeṣin kan tubọ nfi epo si ina, awọn majẹsin alayọnusọ ṣọbọyọke wọnyi ti amọju iwe fẹ da ni ori ru ni o ntu ẹgbẹ Afẹnifẹre, awọn majeṣin wọnyi ko mọ ọrọ tunṣe, obilẹjẹ ni wọn, fọ ẹgbẹ fọ ẹgbẹ ni wọn, bẹnani wọn si ma nfọ ajọ.

ỌRỌ RE O !

# Ema Ka Iwe Irohin Eleti - Ofe

# Iwe Si Olotu

## E Ye Ji Bata Ko Ni Mosalasi

Ẹ jọwọ ẹ ba wa ṣe ikilọ fun awọn ti o nji bata ko ni Mọsalasi ki nwọn ye jale ni ile Ọlọrun.

Laipẹ yi ni ọkunrin kan wa kirun ninu Mọsalasi kan l'Eko; nigbati o ṣe aluwala tan, o si bọ bata ti o wọ si kọrọ kan ninn ile-isin na; nigbati o kirun tan ni o bẹrẹsi tarara wa bata kiri. Awọn ole ti ko nwọn lọ.

O yẹ ki awọn ti o nhu iru iwa bayi mọ wipe idaríjin ẹṣẹ ni awọn wa tọrọ ninu ile Ọlọrun, ko si tun yẹ ki nwọn tun ma da ẹṣẹ kun ẹṣẹ nipa gbigbe nkan oni-nkan nibikibi.

Emi ni
Eko A. Bello

## Oro Aso Ebi

Laipẹ yi, ninu ipade nla ti awọn Ijọ C. M. S' ṣe l'Eko ni Alufa-agba (Bishop) bẹrẹsi tẹmọ nwọn leti wipe ki nwọn ye ko owo wọn le aṣọ ẹbi lori mọ nitoripe ko si anfani kan nibẹ

Mo niran wipe o to ogun ọdun tabi jubẹlọ nisisiyi ti awọn oniwe'rohin ti nṣe kilọ-kilọ fun wa lọ'kunrin lobinrin wipe ki a ṣọra pẹlu aṣọ-ẹbi ti a nra.

Ọpọlọpọ awọn obinrin wa ni o ti fi ọrọ aṣọ ẹbi ba ara wọn jẹ, a nwa owo aṣọẹbi kakiri ti sọ oganlọgọ nwọn di panṣaga.

Ẹ ba wa tun ṣe ikede fun nwọn pe a nra aṣọ ẹbi olo wo iyebiye ko dara.

Emi ni,
Ilesha A. Fatoki

## Ikilo Lori Egbogi Lilo

Ẹ gba mi laye ninu iwe-irohin nyin lati ṣe ikilọ fun awọn ọlọja ti nwọn nta egbogi Oyinbo kiri, ti nwọn ko le ṣe apejuwe lilo rẹ fun awọn ti nwọn nta fun.

Laipẹ yi ni a gbọ wipe ogun igbọnsẹ kan ti awọn kan ni ilu oke ra, ti wọn ko mọ apejuwe lilo rẹ ṣe jamba fun iya ati awọn ọmọ rẹ ti nwọn lo, gbogbo wọn ni o si ku patapata.

Yio jẹ nkan ti o dara pupọ bi awọn olotu Ijọba wa ba le ṣe ikede kakiri igberiko fun gbogbo awọn enia wipe, egbogi ti nwọn ko ba mọ apejuwe lilo rẹ ki nwọn maṣe ra wọn mọ, nitori jamba iku ti o wa nibẹ.

Ọpọlọpọ egbogi buruku ni nwọn nta kakiri nisisiyi ti nwọn npe ni egbogi atẹjẹṣe, nitorina ki a ṣọra.

Emi ni
Ibadan L. A. Amọlẹgbẹ


## E Mase Fomi Sofo Mo



# Nihin, Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)
Ẹ Ku Alaja Ọdun

Emi Ayiluka tun de. Mo si tun ki gbogbo nyin ni ọmọde lagba ku alaja ọdun. Ṣe emi ti sọ fun nyin wipe temi ko ṣoro'? Ọdun Ileya dara pupọ fun mi ; mo je !fun ẹran agbo titi titi, meji ni o ka patapata ninu awọn ehin ẹnu mi.
Ẹnyin Musulumi, kilọse ti wayo fi wa pọ pupọju ninu aiye wa nisisiyi ? Boya ẹ ko mọ ibiti mo mba ọrọ mi bọ. Ọrọ ti emi Ayiluka gbọ ni wipe awọn Alhaji kan pa owo, awọn Alhaji kan si goee lọ. Ẹ jọwọ, ẹ jẹ ki a si dakẹ je ẹ nibiti mo gbe ba ọrọ de yi.
Bi ẹlẹmi mi ko ba gbaa, ma fi ẹnu kan ọrọ diẹ ninu ọsẹ ti o mbọ yi nipa ọrọ awọn Alhaji oni-wayo lagba ati lọmọde
Ẹ jẹ ki nsọ fun nyin, ọpọlọpọ ẹran agbo ni awọn Olowo nwọn ra ti nwọn ko si ri fi pa Ileya, nitoripe ẹru Ọlọrun ni i o raa, ẹru Olọrun ni o si gbe e lọ.

ỌMỌ-JAGU DA PỌ L'EKO

Laipẹyi ni emi Ayiluka lọ si ibi isinku iya wa oninure kan l'Eko ; mo mura dindin, mo tun kan jingin mọ'ju ; a jẹ awọn ọmọ-jaguda nsọ mi. Boya nwọn ṣebi ọkan ninu awọn Oloye ni mi l a t i agbegbe Ijẹsha nitoripe emi pẹlu awọn Oloye Ọwa Ilesha ni a jọ nkakiri lọjọ na. Emi na si gẹẹ fila mi bi ti awọn ara oko.

Awe, ọkan ninu awọn ọmọ-jaguda na fi ọbẹ alafẹfẹ g: mi niapo, o si mu iyoku ninu owo ti mo fẹ fi ṣe igbadun aiye mi ni irọlẹ ọjọ na.
Jamba ọjọ na wa mu mi ṣe iranti iya Ologbe kan ti a npe ni Iya Saro ni igboro Eko l'atijọ, ti o maa nkọrin bayi ti o ba lọ si ibi isinku tabi ibi ere-ṣiṣe: "open your eyes de, ọmọ-jaguda bọku for Lagos".
Nko ni sọ ju eyi lọ, sugbọn ti o ba lọ ba nwọn ṣe ariya nibikibi l'Eko, ni Ibadan, ni Enugu tabi ni Kaduna; ki o jọwọ ṣọra pupọ nitoripe ko si ibiti ọmọ-jaguda kosi. Nwọn wa ninu Ṣọṣi, nwọn nji bata ko ninu Mọsalasi.

ỌKỌ KAN, IYAWO KAN

Bi enia ba pẹ laiye, oju rẹ a ri nkan, sugbọn ju gbogbo rẹ lọ Ọlọrun ma jẹ ki oju gbogbo wa ri iri-ku-ri. Sibẹsibẹ ni ilu Ghana ọrọ ti di ọrọ ekun kan, ọmọ rẹ kan; iyawo kan, ọkọ kan. Ofin tuntun ti de wipe ẹnikan ko gbọdọ fẹ obinrin meji sinu ile. Ẹnikẹni ti o ba gbe iyawo meji sile Ijọba a fi kele gbe e; ninu ki o san ọdunrun pọnun tabi ẹdẹgberin pọnun tabi ki o lọ ṣẹwọn ọdun meje.
Ori awọn obinrin Ghana mọ dara o! Mo fẹ ṣe ikilọ pataki fun awọn Ọlọmọge wa ni Nigeria pe ki nwọn ṣọra pupọ, ki nwọn maṣe pantete ọkọ won rara, nitoripe laipẹ yi awọn obinrin Aganyin a kun ilu yi jaburata. Ka mu ẹgan kuro nibẹ, a w ọ n obinrin Ghana gb'afẹ pupọ. Ẹniti o ba fi ọkọ rẹ ṣe fari nwọn a jagba mọ lọwọ nitoripe ọkọ ṣọwọn pupọ ni Ghana nisisiyi.

AKA'NIA, Ẹ KA AFỌJu PẸLU O

Ẹ jọwọ ẹnyin ọkawe mi boya nwọn ti ka nyin, sugbọn nibo ni nwọn a ti ka emi AYILUKA ? Ṣe ni abẹ - b u k a awọn "Ọmọmeji d'awosilẹ" ni, tabi ni Abẹ-buka ni ọja Oyingbo tabi ninu isọ awọn alaṣọ - Oke ni Jankara ni ?
Ayiluka ko gbe ibi kan; emi lọhun, emi nihin, emi na nibi gbogbo. O jẹ nkan ti o lẹtọ ti a ba l e k a a w ọ n afọju ati awọn arọ, ti o mbẹ ni Nigeria, nitoripe m o g b ọ wipe afọju ati arọ pọ toi.ẹge ni Ipinlẹ Ariwa ati pe awọn na to da ilu kan duro fun ara wọn, ki a si fun wọn n l'Ọba tabi Balẹ ti nwọn yio maa pe ni "Seriki Mekafo".

---

# Awon Nka Enia Ni Ilu Ripe Won Ka o Mowon, Fun Idagbasoke Ilu Re

(LATI ỌWỌ J. ỌLA WINS)

Gẹgẹbi gbogbo awọn iwẹ irohin nke fun wa lọtun, losi, lojojumọ ati ni ọsọsẹ wipe jẹ ki awọn akọwe ti nkan enia ka ọ maṣe sa s'ẹhin, bọ si gbagba, da'rukọ ara rẹ fun wọn. Gbogbo nkan ti nwọn ba bere lọwọ rẹ, da wọn lohun pẹlu ayọ ati ifẹ, nwnọ ki iṣe ọta wa, orẹ wa ni wọn jẹ.

O to ọdun mẹwa s'ẹhin ti a ti ka enia gbẹhin, ẹpọlọ pọ aṣiṣe ni aṣe, ẹlomiran bi ọmọ mẹfa, o pe ni mẹta o ro wipe boya nitori owo-ori tabi owo-ode ti a nsan si apo ijọba ni ẹlomiran ẹwẹ, da orukọ ti ki iṣe tirẹ, ẹru nba ko mọ ohun ti yio jẹ abọ nkan ti awọn akọwe ti nkania yio jasi, boya ọrọ le ba ẹhin yọ.

Bi a ba nka iwe Irohin, yala ti ojojumọ ni tabi ti ọsọsẹ ni, ao ma ri ka wipe ilu wa nfẹ omi ẹrọ siṣe, ilu wa nfẹ ina mọnamọna, ile-ifowo-ranṣẹ ati bẹẹbẹ lọ. Enia kika yi ni yio fun awọn Ijọba ni anfani lati mọ ohun ti o tọ si ilu ni ilu kọkan.

(Wo yoku loju ewe keje)

---

# Omi Layo Na



Awọn ẹgbẹ agba-bọlu afẹṣẹgba ti Aṣọle ti Cardiff (Goalie) Vearncombe lu gbadi ihamọ lati gba bọlu kuro pẹlu aṣiwaju ti Arsenal, Strong (N0. 9) ati ọmọ ẹgbẹ t i Cardiff paapa Mel Charles (N0. 6 ti nwọn gba lọdọ Arsenal laipẹ yi.
Akatakiti yi ṣẹlẹ nibi ere bọlu t i nwọn gba nile Arsenal ti o jasi ọkọkan (1-1) ọmin

## Arewa Obinrin Agbaiye Ti Odun 1961



Awora ti a nwo yi n i t i Omidan Rosemarie Franlan ti o rẹrin idunnu nigbati o yege ninu ere idije fun arẹwa obinrin larin ilu merindin-logoji ti nwọn ṣe ninu ile ijo ni Gbọgan Lyceum nilu Oyinbo laipẹ yi.

Ọmọ ọdun meji-din-logun Rosemarie ọmọ ilu Lancashire ti yege ti Arẹwa obinrin ti ilu Oyinbo tẹlẹ ri, eyiti o tun yege yi jẹ ti agbaye, o si ni ẹbun ẹgbẹtaladin-ọgọrun pọnun ninu (£2500).

## Tisa Kan Ku Si Ile'we Ni Ibinni

BINNI - Idamu ati jinni-jinni mu awọn ọmọ ile ẹkọ kan ti nwọn npe orukọ rẹ ni First Baptist Church Mission School, ni Binni, nigbati nwọn ri ọkan ninu awọn olukọ wọn, J.S. Johnson, ti o ṣubu lulẹ ti o npọka iku.

(Wo yoku loju ewe keje)

## Ogbeni Kan Mu Siga Titi Efin Re Paa

AMẸRIKA-Gbogbo awọn ọrẹ ati ara adugbo ọkunrin kan, ti nwọn npe ni Edwin Green, [ti o ngbe New Orlean ni ilu Amẹrika ni o pejọ siba-siba si kotu adajọ agba lati gbọ ọrọ ẹjọ ti awọn ẹbi Ọgbẹni Green ti o mu siga titi ti efin rẹ fi pa a ku patapata.

Ninu iwe-ẹjọ ti awọn ẹbi Ologbe na pe awọn Oyinbo Onitaba ti o nwe siga ta ara Amẹrika kan, nwọn ni awọn ni o ṣe onfa iku Green nitoripe Ologbe na ki i mu nkankan ju siga ti awọn Oyinbo yi nta lọ; nigbati o jalaisi, awọn si gbe oku rẹ fun awọn ogunna-gbogbo awọn oniṣegun lati mọ arun ti o paa.

Lọya awọn ibatan Ologbe Green na ni awọn Dokita na ni arun kan ti nwọn npe ni Cancer (Ọgbẹ'nu) ni o paa; ko si si nkankan ti o fa arun na ju siga awọn Oyinbo yi ti o mu lọ.


## OKUJA WO'LU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O RA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO ṢE LE RA OMIRAN, EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE ṢE TI ỌJA LE FI MA TA

BI IṢU AKARA GBIGBONA.



## Ema Ka Iwe Irohin Eleti - Ofe

Ti o kun fun Irohin Aladun L'osose

# Television Service For Sierra Leone Soon

FREETOWN- A television service is to be established in Sierra Leone this year, it is announced by the country's Minister of Information and Broadcasting, Mr. John Nelson-Williams.

It will be nationally owned and controlled with a transmitter sited near Freetown and linked to studios in the capital. It is hoped that the first test transmissions will begin by 1st July and that the service will be opened about a month later.

The service will be operated by a consortium consisting of Scottish Television, Television International Enterprises and the National Broadcasting Company of America for a limited period during which Sierra-loneans will be trainedfully in techniques necessary to run the service.

It is hoped that initially the station will be "on the air" from seven until eleven each day. Special emphasis will be put on education programmes and a time is to be selected for schools television.

# "Boarding School Afloat" Voyage To West Africa

LONDON - Some eight-hundred British and French school-children are to make an educational cruise to West Africa in August under the first project organised by Britain's newly formed Council for African - British Relations.

The "boarding school afloat", as it was called by the Council chairman, Sir James Robertson, formerly Governor General of Nigeria, will visit Senegal, the Gambia and Morocco.

The british contingent, who will pay £48 per head for the voyage, will be drawn from the main grammar and public schools of the country. Also on board the motor ship DEVONIA, which has been specially fitted out for educational cruises by the British India Steam Navigation Company, will be twenty senior school-boys from Senegal to act as guides. At each port of call the children, whose ages will range from thirteen to eighteen, will enjoy shore excursions and meet local young people.

# Nwon Nka Enia Ni Ilu, Ripe Won Ka O Mowon, Fun Idagbasoke Ilu Re

(O bere loju ewe karun)

Ijoba fe mo iye omo ti o wa ni ilu re, lati mo iru ile-eko ti nwon yio ko fun ilu re, ilu miran kere, o ni ile-eko giga, sugbon awon omo ilu ko to, ana danu ni inawo be jasi, ilu miran tobi ko ni ile-eko giga, wahala lo je fun awon omo ilu be; obi miran ni owo eko giga sugbon bi a ba tun fi owo oko kun, inira de; nitori idi eyi, opolopo omo ni ko le ka iwe mo: beni ori won ya si iwe.

Laije wipe Ijoba mo iye awon enia re, omode, agbalagba, okunrin ati obinrin, Ijoba ko le mo bi o ye ki e ni ile-oogun tabi ko ye, e ma se fi ara 'nyin pa mo loteyi, o ye ki mo wipe owo ni Ijoba Apapo ni lati na lori oro ika'nia yi. O ye ki a mo riri owo na, ko si ona ti a le gba mo riri owo na ju wipe ki a dahun gbogbo nkan ti awon akowe ti nka enia ba bi wa daradara.

Ati wipe iru işe aje ti Ijoba fe da sile ninu eto inawo odun marun, bi a ba ka enia tan, nigba na ko ni si aşişe rara nipa gbigbe ile-işe-aje fun ilu ti o tobi loju ti awon enia ilu be kere. E ma fi aşişe gbe anfani nyin sonu, nitoripe [illegible] kan ti o ba sonu [illegible], a ko le ri mo laelae.

Orişişi ni awon enia npe iye awa omo Nigeria, elomiran ni 35,000,000, elomiran 40,000,000, [illegible] wa ni ki a gbagbe [illegible] ki a ka ara wa, lehin na ni a o to le mo ipo [illegible] ninu orilede ti enia [illegible]. Mo fi iyonu Ol[illegible] b[illegible] nyin ki e maşe puro fun won; bi awon akowe ko bá ti ka o, asiko ko ti koja o, yara to awon akowe lo ki nwon ka o, "aso ti a [illegible] a ko ti ran ko mai ti [illegible] tita", bi nwon ko ba ti ka o, ko mai ti boo! lo ba won ki won ka o, ki idera ba le ba o ati omo re. Ki gbogbo awa omo Nigeria wa nia ioki.

Jeki nwon ka o o!

---

## Isinku Olanigbin Dun, O Larinrin

Ni ojo Aiku ti işe ojo kefa oşu yi ni Ogbeni Abudu Salami Olanigbin jade laiye lati inu ile re, 62, Obun Eko Street, l'Eko, nigbati o di eni odun merindinladorin, nwon si sin oku re ni ojo keji ni deede agogo merin irole ni Ite-oku Ikoyi.

Ero po ni ibi aşeye isinku na, nwon si gbe opa Opa wa tibe pelu. Awon omo oloku, awon bi Ogbeni Ayinde Shonibare, Alimi Shonibare ati arewa Hannota Apatira na wabi wosi owo, nwon ha'wo, nwon si se orişirişi onje adidun.

Ki Oluwa tun ehin oku na şe o.

# Oloye Awolowo bere Irin Abewo Re Si Oshun

OLOYE Ọbafẹmi Awolọwọ ti iṣe Akonijẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre, ti edeaiyede be silẹ larin ẹgbẹ Afẹnifẹre na, bẹrẹsi irin abewo rẹ lọ si ilẹ Ọshun lati ṣe alaye ohun ti ẹgbẹ Afẹnifẹre duro le lori fun awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ, ki ẹjọ ipade ipari ọrọ wọn to pe ni ọjọ Satide oni.

Bakanna ni a gbọ wipe Oloye S. L. Akintọla paapa ti tun tọ lẹhin lọ si Ọshun fun alaye bakan na. A si gbọ wipe ọpọlọpọ awọn enia jankan-jankan ti o mu opo ijọba dani ni nwọn ba wọn lọ pẹlu.

Ki a ma reti abọ wọn si rere.


## NIGERIAN PORTS AUTHORITY

VACANCY - SUPERINTENDENT ELECTRICAL ENGINEER

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to the post of Superintendent Electrical Engineer in the Engineering Department of the Authority.

QULIFICATIONS

Candidates must be a Corporate Member of the Institution of Electrical Engineers or equivalent and have experience in large workshop installations, or in Shipyards and dock and harbour installations. Experience in radio work or in an allied electronic field is desirable. It is essential that candidates have extensive practical knowledge of most facets of maintenance and installation of electrical switchgear, plant and associated equipment.

DUTIES.

The successful candidates will directly responsible to the Chief Engineer for the Electrical Section of the Engineering Department. The work involved covers a wide field, including High and Low Tension distribution in Quays and Dockyards, Quay Cranes, Lifts and Mobile Plant, Dockyard Machinery, and electrical installations in the Authority's floating dock, dredgers, colliers, etc. and also covers V.H.F. and H.F. radio. He will also be responsible for the maintenance of domestic electrical apparatus in the Authority's quarters, etc. and outstations.

SALARY.

Scale 2, £1,815 x 55 - £2,035 for indigenous candidates. Expatriates will be on a fixed salary of £2,035 per annum plus £300 per annum overseas pay and on contract for two tours; the first tour being on probation.

METHOD OF APPLICATION:

Application forms are obtainable from the Personnel Manager, Nigerian Ports Authority, Apapa dockyard, and should be completed and returned so as to reach him not later than 31st May, 1962. Candidates in the service of the Government or a Corporation must submit their applications through their Heads of Departments who will forward them to the Personnel Manager along with Confidential Reports. Persons without requisite qualification and experience as detailed above need not apply.

N.P.A. Notice No. 710. BAYO KEHINDE
17th May, 1962. Secretary to the Authority.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370; Olotu L. A. OJO, 12 Inabere Street, Lagos.

# Akara Tu Sepo

(O bẹrẹ loju ewe kini)

enia si fi ara mọ ti Oloye Akintọla, ni nwọn si nsọ bayi wipe "bi a ba f'agbo fun egungun a ju okun rẹ silẹ ni."

Bi awọn ọmọ ogun Ọlọla Oloye Awolọwọ ti nke "Ijaṣi Oroo !!!" bẹni awọn ọmọ ogun Akintọla nṣe "Ogun yee !!!" Ọrọ wa di bi igbati epo oyinbo dapọ mọ erupẹ, akara wa tu se'po. Awọn ọrẹ meji nkọ ohun arawọn, ẹgbẹ nda si ọna bi meji tabi mẹta. Awọn Ọgagun mejeji gbe ara wọn sori iwọn, bayi ni ẹgbẹ Afẹnifẹre ti nri wọ omi lọ.



OLOYE AWOLOWO
Olotu Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Ẹnyin agba'gba enia ni Oluwa Ọlọrun fi ṣe "Majẹobajẹ" aiye, ọrọ yi di ọwọ nyin o. Bi nwọn ba ni o di ọwọ Imale, Imale a ni o di ọwọ Allah. Ẹnyin ọjẹ ọmọ Elegun, abilọjẹ ẹtun ọjẹ se !

## Taiku, Olorin Ku Si'bi Aisun Odun Ni Ikorodu

Ikorodu—Bi o kolọ, ki o yago lọna ni olukuluku nsare nigbati ariwo ta gee ni Ikorodu nibiti nwọn nṣe ariya aisun ọdun Ileya lọwọ ti nwọn wipe ọkunrin akọrinta kan ti o njẹ Taiku, Olorin, ara adugbo Ijomu, ṣubu lulẹ larin ero-ṣiṣe na, o si ku.

Onirohin Eleti-Ọfẹ fiye wa wipe ni owurọ ọjọ na, ara Taiku ya daradara, kosi nkan ti o ṣe ki o to lọ si ibi ariya aisun ọdun na, ti nwọn nṣe ni Itun Meko; on na bẹrẹsi kọrin, o si njo, nibiti nwọn gbe ti nfi owo yọesi lọwọ ni ọlọjọ ti de baa.

# Moise Tshombe J'owo Sile

Elisabethville— Alakoso Ijọba Katanga ti o ti da duro kuro lara ilu Kongo, Ọgbẹni Moise Tshombe ti sọ fun awọn Oniwe irohin nilu Elisabethville wipe on ti ṣe tan lati gbe ijọba Katanga fun Ijọba Kongo nilu Leopoldville ti o jẹ ijọba arin ilẹ Kongo.

O fihan wipe ninu ọdun 1960 ni awọn ti yapa lọ kuro lara ijọba Kongo. A tipe gbogbo awọn enia on mọ wipe ipapọ ilu Katanga pẹlu ijọba ilẹ Kongo yio ṣe anfani fun ire ilẹ enia dudu.